**OWE**

Ikun nj'ogede, Ikun nrędı, Ikun ko ma pe ohun ti o dun ni i pa ni.

# Irohin Yoruba

VOL IX No 464 — MONDAY MAY 31, 1954 — KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba

# Awon Ti O Pa Apalara Ti Ku Iku Oro

AWỌN mọkanla wọnyi, Joseph Ogundipẹ, Lasisi Oluwa, Nọsiru Ajọsẹ, Yinusa Kosẹgbe, Lamidı Akinwumi, Isiaka Ajana, Karimu Ayinde, Akanbi Ọmọba, Ashimi Musẹndiku, Mustafa Ọtẹka ati Raimi Ọtẹka ti Ijọba ba ṣe ẹjọ apania nipa Alfa Arọwasi Bisiriyu Apalara ti nwọn pa ni Oko-Baba Ebute Mẹta nibiti o gbe nrọ waasi, ni nwọn ti yẹgi mọ wọn lẹsẹ l'ọgba ẹwọn ni owurọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn ọsu yi.

Gẹgẹ bi idajọ ti nwọn ti gba ni Kotu nla l'Eko ni ọjọ kẹrinla oṣu kẹwa ọdun ti o kọja pe, nwọn jẹbi ẹsun apania lori iku Apalara, awọn na si yẹ fun iku oro, pe ki nwọn so okun mọ nwọn lọrun ki nwọn o si ma a fi dirodiro titi ti nwọn o fi ku.

Nigbati Ọlọla Adele Gomina ba awọn Igbimọ Idajọ ( Privy Council) rọ jiroro lori ọran ẹjọ wọn na ni nwọn ba pinnu pe awọn fi ara mọ ẹtọ idajọ ti Kotu ti da fun wọn pe, gẹgẹ bi ofin, nwọn jẹbi iku. Nitorina ki nwọn lọ pa awọn mọkọkanla ra. Eyi ni ipari ẹjọ iku Alfa Bisiriyu Apalara o.

## Ojeleye Di Balogun Apatere

APATERE-IBADAN: Ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kerindinlogun oṣu keji ọdun yi ni awọn oṣelu, oloye, ati awọn enia pataki pataki miran ati awọn orişirişı ẹgbẹ pe jọjọ si ile Balẹ Apatere, ọsukuluku wọn si ṣe ẹsọ ti o ga lọla.

Orişirişi itu ndun, ọpọlọpọ awọn alabaşẹyẹ ọjọ na si nla ijo ayọ mọra lati arọ kutu h?? titi ilẹ fi şu, ero ọjọ na buaiya.

Nigbati o ma fi di agogo mọkanla arọ ẹsẹ gbogbo enia ti pe sibẹ, nwọn fẹrẹ le ma şubu le ori ara wọn. Ni ọnkan bi agogo kan ọsan ọjọ na Olo-

(Lati oju ewe kini)

# Ise Ti Awon "Action Group" Ti Se Si Ilu

ISE ti awon "Egbe Action Group" ti ise alakoso Ijoba Iwo-Orun Nigeria se niwon igbati Ijoba bo si owo won ko se ka tan, enikeni ni o si mo daju pe ninu gbogbo awon Egbe oselu ti Ijoba ilu wa ni ikawo won ko si eyiti a le fi we Egbe Action Group nipa ki a wi be e ki a se be e.

Niru oşu kẹta ọdun 1950 ni Ọlọrun yan Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ lati da Ẹgbẹ na silẹ. Nigbati ijanu Ijọba Iwọ-Orun Nigeria si bọ si ikawọ wọn ninu oşu kini ọdun 1952, nwọn si ṣe ikede fun gbogbo enia, awọn inkan ti nwọn gbero lati ṣe si ilu bi-

Lati mu ki iṣẹ itọju ilera pọ si yika ilu gbogbo.

Lati mu ki iṣẹ ẹkọ tubọ pọ si yika ilu gbogbo.

Lati jẹki omi-ẹrọ yika gbogbo ilu.

**Lati Owo Ayo Akinsanya**

Nisisiyi o tọ ki a si mọ bi nwọn ti mu ileri na ṣẹ si, eyi ni yio mu ki a ṣe isipaya rẹ fun gbogbo enia eyiti awọn ti ṣe ati eyiti nwọn ngmura rẹ lati ṣe.

### ẸKỌ

Eyiti o fi yatọ fun Ijọba atijọ, ti nwọn nfun awọn akẹkọ ni ẹkọ ọlọfẹ lori awọn inkan ti ko wulo fun ilu, Ijọba Action Group ti fi ẹkọ ọlọfẹ fun awọn akẹkọ ti o ni lati kọ awọn iṣẹ wọnyi:- Arts, Science, Economics, Business Management, Secretaryship, Accountancy, Banking, Co-operation, Menography, Solicitorship, Insurance, Chemical, Civil, Mechanical Electrical,

( Wo oju ewe kẹrin)



Aworan eke yi ni ti awọn ọrẹ ati ojulumọ ti o wa ba ọkọ Iyawo, Ebenezer Okulaja ṣe aisun igbeyawo ti nwọn si tun wa si Ṣọọsi ni ọjọ keji ki nwọn to ma ri Iyawo mọ.

# IYAWO KO WA SE IGBEYAWO

**IROHIN yi je eyiti o mu ibanuje okan ba t'oko t'aya, ti awon mejeji si fi se ipinnu airotele pelu ibanuje ati okan gbigbona. Ipinnu oko ni pe, o se on ki ! o se on po !! on ko tun ba omidan kan damoran "a fe'ra eni - a ko fe'ra eni mo". Iyawo si pinnu pe o se on ki ! o se on po !! on ko tun ni de Eko mo" nigbati nwon pari ife odun meta sori aisegbeyawo.**

Ni ọjọ Aiku ti işeọjọ keji oşu yi ni Ọgbẹni Ebenezer Ademọla Okulaja, akọwe awọn Oyinbo Onişowo G. B. Olivant l'Eko lọ si Şọọşi Italupe (Italupe Anglican Church) Ijẹbu-Ode ni ireti a ti gbe Omidan B. O. Ọnafẹkọ ni Iyawo, ti nwọn ti nfẹ ara wọn bọ lati bi ọdun mẹta sẹhin ki nwọn to fi adehun igbeyawo si ọjọ yẹn.



Omidan B. O. Ọnafẹkọ on ni ẹniti Ebenezer Okulaja fẹ gbe ni Iyawo şugbọn ti o taku ti ko şe igbeyawo.

Şugbọn iyanu nlanla ni o jẹ fun ọkọ-iyawo ati ogunlọgọ enia, l'ẹbi, l'ọrẹ l'ojulumọ ti nwọn ba ọkọ iyawo wa si Şọọşi lati ri i pe iyawo fi ake kọri ko yọju si ibẹ rara, nitori ti Iya-iyawo ti tẹ ohun rẹ tele pe, on ko fẹ igbeyawo-Şọọşi afi ti Kotu (Court Marriage) Baba ọkọ si ti ba ọmọ rẹ pinnu pe Igbeyawo-Şọọşi ni on fi ara mọ.

Ki a ma ta ọrọ gun lọ lati mọ b yi ri gbogbo awọ enia ti o wa si Şọọşi fun ayẹye igbeyawo na şe tuka lọ ile wọn nigbati nwọn ko ri iyawo, bẹ ẹ awọn ọrẹ ọkọ-iyawo ti fi ọkan ọkọ bale pe yio bọ si gẹgẹ bi ohun ti nwọn ti gbọ lẹ si Iyawo, eyi mu ki ọkọ-iyawo o ti bẹrẹ si şe inawo lati igbati ọjọ igbeyawo ti ku ọla, bẹni nwọn şe aisun mọju ni ile ọkọ-iyawo, ti nwọn nse fi nwọn nsọ, ti nwọn njẹ ti nwọn nmu titi ilẹ ọjọ na fi mọ. Ni ọjọ igbeyawo, ọkọ-iyawo si ti fi ile p'ọti o ti t'ona f'oka pe ti nwọn ba ti ti Şọọşi de ki nwọn le bẹrẹ ayẹyẹ igbeyawo.

Bayi ni igbeyawo Ebenezer Ademọla Okulaja pẹlu Omidan B. O. Ọnafẹkọ na şe pari laisi atunşe kankan mọ, ọkọ-iyawo na si ti şiro gbogbo owo ti o na le ọdọmọde-binrin na lo i lati igbati nwọn ti nfẹ ara wọn ati owo - idanọ si ponun mẹtaleladọta ati

(Wo oju ewe kẹrin)

**PR-GRESS**

**O! ARE U MISSING**

16 hours of it for less than

3d A DAY --- GET REDIFF-SION

